# AJINDE IRETI ONIGBAGBỌ́

**1 Kọrinti 15:1-58**

**ẸKỌ 379 -- FUN AWỌN ỌDỌ**

**AKỌSORI: "Kò si nihinyi: nitori o ti jinde gẹgẹ bi o ti wi" (Matteu 28:6).**

## ALAYE

### Akoko Ajinde Kristi

Paulu kọwe si awọn ara Kọrinti lati rán wọn leti gẹgẹ bi Ihinrere ti niyelori to, lati sọ ero wọn ji lọtun nipa Kristi – igbesi-ayé Rẹ̀, iku rẹ̀, ati ajinde Rẹ̀. Ohun rere ni fun wa lati ṣe àṣaro lori ohun ti Kristi ṣe fun wa ati ohun ti O jẹ́ fun wa. A ti n kẹkọọ nipa apẹẹrẹ ti Kristi fi lelẹ fun wa nipa aye Rẹ̀. Ọpọlọpọ igba laaarin ọdun ni a ti n mu un wá si iranti wa pe Kristi fi ẹmi Rẹ̀ lelẹ fun ẹ̀ṣẹ araye (Heberu 9:28; 1 Peteru 2:24). A n kọrin nipa agbelebu ati agbara ti o wà ninu Ẹjẹ rẹ̀. Nigba ti a ba n jẹ Onjẹ-alẹ Oluwa, a n ṣe iranti Ẹjẹ Rẹ̀ ti a ta silẹ ati Ara Rẹ̀ ti a palara. Ni akoko Ajinde yii, ẹ jẹ ki a ronu paapaa lori ajinde Rẹ̀. Ki i ṣe Kristi ti o kú ni awa n sin, ṣugbọn ti wa ni Olugbala ti o wà laaye Ẹni ti o jinde fun idalare wa (Romu 4:25).

### Awọn Alaigbagbọ́

Ni akoko Paulu, awọn eniyan kan wà ti wọn kò ni igbagbọ́ ninu ajinde awọn oku. Laaarin wọn, ninu awọn Ju, ni awọn kan wà ti a n pè ni Sadusi (Luku 20:27). Paulu waasu nipa ajinde nitori pe o gba a gbọ́. Gẹgẹ bi ẹri rẹ̀ nigba ti o duro niwaju Agrippa, lati Ọrun ni Paulu ti gba igbagbọ́ ti o ni nipa ajinde. (Iṣe Awọn Apọsteli 26:13, 22, 23). Paulu waasu ajinde ki awọn ọkan ba le ri igbala. O ṣe danindanin pe ki a gba ajinde Jesu gbọ ki a ba le là. "Ọ̀rọ na wà leti ọdọ rẹ, li ẹnu rẹ, ati li ọkan rẹ: eyini ni, ọ̀rọ igbagbọ́, ti awa nwasu; pe bi iwọ ba fi ẹnu rẹ jẹwọ Jesu li Oluwa, ti iwọ si gbagbọ́ li ọkàn rẹ pe, Ọlọrun ji i dide kuro ninu okú, a o gba ọ là" (Romu 10:8, 9).

### Awọn ti o Gbagbọ́ nigba Majẹmu Laelae

Awọn eniyan wà ni akoko Majẹmu Laelae ti wọn ni igbagbọ ninu ajinde okú. Wọn gbagbọ nitori pe Ọlọrun ni o fi hàn fun wọn. Dafidi sọrọ nipa jiji ni aworan Oluwa (Orin Dafidi 17:15). Jobu wi pe, "Emi mọ̀ pe Oludande mi mbẹ li ãyè, ati pe on bi Ẹni-ikẹhin ni yio dide soke lori erupẹ ilẹ. Ati lẹhin igba awọ ara mi, ti a ti ke e kuro bi iru eyi, ati laili ẹran ara mi li emi o ri Ọlọrun, Ẹniti emi o ri fun ara mi, ti oju mi o si wò" (Jobu 19:25-27).

Paulu n sọ nipa akọsilẹ awọn wolii nigba ti o wi pe Kristi jinde ni ọjọ kẹta gẹgẹ bi Iwe Mimọ́ ti wi. Ọpọlọpọ ninu awọn wolii igba Majẹmu Laelae ni o gba ajinde gbọ́, nitori pe wọn kọ akọsilẹ nipa rẹ̀. Asọtẹlẹ wọn jẹ ẹri nipa ajinde.

### Awọn Ifarahàn Kristi

Yatọ si igbagbọ ailabula ti o wà lọkan awọn ẹni ti a ti gbala, awa pẹlu lode oni ni otitọ ti o fidimulẹ ninu itan pe Jesu jinde kuro ninu okú. Angẹli ni sọ fun awọn obinrin ti o lọ sinu iboji ti o ṣófo pe Jesu ti jinde (Marku 16:6). Jesu fara hàn fun Maria Magdalene (Marku 16:9), ati fun meji ninu awọn ọmọ-ẹyin Rẹ̀ ni ọna Emmausi (Luku 16:9), ati fun Simoni Peteru (Luku 24:34). Awọn ọmọ-ẹyin mọkanla ri I, wọn si ba A sọrọ (Marku 16:14). Ọpọlọpọ ni o ri I bi O ti n goke re Ọrun (Iṣe Awọn Apọsteli 1:9). Gbogbo awọn wọnyii jẹ́ ẹri pe Kristi jinde.

Paulu kà a si ohun pataki lati fi idi otitọ ajinde Kristi mulẹ nitori eyi ni ipilẹ awọn Onigbagbọ. On ni ipilẹ igbagbọ ati ireti wa.

### Akọso

Ninu ẹkọ wa nipa awọn ọjọ ajọ pataki ti awọn Ọmọ Israẹli maa n ṣe, a kọ́ ẹkọ́ pe ni ọjọ ti o tẹle Ọjọ Isinmi Irekọja, wọn a maa mú ọrẹ akọso wá fun Oluwa, lati ya ikore si mimọ́ ati lati mu ki o daju. Ni ibẹrẹ ikore, ki awọn Ọmọ Israẹli to jẹ ninu eso oko wọn, wọn yoo mu ọrẹ -- ẹbọ akọso wá fun Ọlọrun. Wọn a maa ṣe irubọ yi ni ọjọ kẹta lẹyin ti wọn ba ti pa ọdọ-agutan irekọja. Ninu 1 Kọrinti 15:20 a ka pe Kristi "ti jinde kuro ninu okú, o si di akọbi ninu awọn ti o sùn." Jesu ni ẹni kin-in-ni ti a ji dide kuro ninu okú lọna bayii. Ajinde Rẹ̀ jẹ ohun ẹri nipa ajinde ti wa – ireti Onigbagbọ́.

Ni akoko işẹ-iranşẹ Jesu laye, O ji oku dide (Matteu 11:5). Jesu duro lẹba iboji Lasaru ẹni ti o ti kú ni ọjọ mẹrin sẹyin. Lasaru jinde (Johannu 11:43, 44) nigba ti Jesu wi pe "Lasaru, jade wa." A kà nipa awọn ẹlomiran ti Jesu sọ di alaaye -- ọmọbinrin Jairu (Matteu 9:25), ati ọmọ opó Naini (Luku 7:15); şugbọn Kristi jinde lati wà laaye kò si ni kú mọ́ (Romu 6:9, 10). A kàn An mọ agbelebu, "şugbọn Oun wà lãye nipa agbara Ọlọrun. . . . . awa o wà lãye pẹlu rẹ̀ nipa agbara Ọlọrun si nyin" (2 Kọrinti 13:4). Jesu wi pe, "Nitoriti emi wa lãye, ẹnyin o wà lãye pẹlu" (Johannu 14:19).

**Ajinde Kin-in-ni**

Ikú ni idajọ ti Ọlọrun mu wa sori ẹda nitori ẹşẹ Adamu ninu Ọgba Edẹni (Gẹnẹsisi 3:19). Nitori pe Adamu şẹ, "a si ti fi lelẹ fun gbogbo enia lati kú lẹkanşoşo, şugbọn lẹhin eyi idajọ" (Heberu 9:27). Bi o ti şe pe iku ti ipa Adamu wá (1 Kọrinti 15:21, 22), ẹni ti a pe ni Adamu keji tabi Adamu ikẹyin. Ohun ti o şe pataki ju lọ ni igbesi-ayé Onigbagbọ́ ni lati wa ni imurasilẹ fun ajinde kin-in-ni. Gbogbo ilepa Paulu ni lati wà ninu ododo ti Ọlọrun nipasẹ igbagbọ, bi o le şe ki o le de ibi ajinde kin-in-ni (Filippi 3:9-11). Awa i ba jẹ le ni ilepa kan naa lọkàn lati de opin ire-ije naa lai ro ohunkohun ti yoo gbà wá! Paulu ni ireti iyanu yii ninu ọkan rẹ. Bayii ni eto ajinde ti ri: "Kristi akọbi; lẹhin eyini awọn ti işe ti Kristi ni bibọ rẹ̀," i baa şe pe wọn ti kú tabi wọn wà laaye. "Nitori Oluwa tikararẹ̀ yio sọkalẹ lati ọrun wá ti on ti ariwo, pẹlu ohun olori awọn angẹli, ati pẹlu ipè Ọlọrun; awọn okú ninu Kristi ni yio si kọ́ jinde: nigbana li a o si gbà awa ti o wà lãye ti o si kù lẹhin soke pẹlu wọn sinu awọsanma, lati pade Oluwa li oju ọrun: bẽli awa o si mã wà titi lai lọdọ Oluwa" (1 Tẹssalonika 4:16, 17). Eyi yii ni ajinde ekinni, "olubukun ati mimọ́ ni ẹniti o ni ipa ninu ajinde ekinni na, . . . . nwọn o jẹ alufa Ọlọrun ati ti Kristi, nwọn o si mã jọba pẹlu rẹ̀ li ẹgbẹrun ọdun." Şugbọn awọn okú iyoku kò wà lãye mọ titi ẹgbẹrun ọdun naa yio fi pé (Ifihan 20:5, 6).

**Ajinde Awọn Okú**

Ninu ẹri Paulu niwaju Fẹliksi, baalẹ, o si pe, "Bẽli emi nsin Ọlọrun awọn baba wa, emi ngbà nkan gbogbo gbọ́ gẹgẹ bi ofin, ati ti a kọ sinu iwe awọn woli: mo si ni ireti sipa ti Ọlọrun, eyi ti awọn tikara wọn pẹlu jẹwọ, pe ajinde okú mbọ̀, ati ti olõtọ, ati ti alaişõtọ" (Işe Awọn Apọsteli 24:14, 15). Jesu kọ́ awọn eniyan pe; "Gbogbo awọn ti o wà ni isà okú yio gbọ́ ohun rẹ̀. Nwọn o si jade wá; awọn ti o şe rere, si ajinde iye; awọn ti o si şe buburu, si ajinde idajọ" (Johannu 5:28, 29). Asọtẹlẹ Daniẹli wi pe awọn miiran yoo ji dide si itiju ati ẹgan ainipẹkun (Daniẹli 12:2). Eyi yii ni idajọ ti yoo jẹ́ ipin awọn ti o kuna lati mura silẹ lati pade Ọlọrun.

**Ni Aworan Rẹ̀**

Jesu wi pe, "Emi nlọ ipèse àye silẹ fun nyin. Bi mo ba si lọ ipèse àye silẹ fun nyin, emi o tún pada wá, emi o si mu nyin lọ sọdọ emi tikarami; pe nibiti emi gbé wà, ki ẹnyin le wà nibẹ pẹlu" (Johannu 14:2, 3). Ni işẹju ààyá, a o pa awọn eniyan Ọlọrun lara dà. Dipo ti wọn i ba fi wà ninu ara ti aye yii – eyi ti o mọ irora, aisan, jamba, ati ailera -- wọn o dabi Rẹ̀ (1 Johannu 3:2), pẹlu ara ti ẹ̀mi, ti Ọrun ti ki yoo kú mọ́ (Luku 20:36). A ti fi ara kikú wé ara ajinde gẹgẹ bi horo ọka ti a gbín lai si ọkan ninu aşọ daradara ti o wà lara eehu rẹ̀ nigba ti o ba yọ: ehu, şiri ọka, ati ikore.

Onigbagbọ ni ireti iyanu – lati wà pẹlu Jesu ati lati dabi Rẹ̀, nipasẹ işẹgun ti O n fun ni. Bi ireti yii ba jẹ́ ti rẹ, maa duro şinşin, lai yẹsẹ, maa şọna, maa reti, ki o si maa şişẹ titi Oluwa yoo fi dé.

**AWỌN IBEERE**

1 Bawo ni a şe mọ pe Kristi jinde kuro ninu oku?

2 Ki ni ajinde jẹ?

3 Bawo ni eniyan şe le mura silẹ fun un?

4 Ki ni şe ti awọn kan yoo jí si itiju ti awọn miiran yoo si jí si ìye ainipẹkun?

5 Ki ni yoo şẹlẹ nigba ti ipe Oluwa ba dún?